# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA
No. 754. MONDAY, JULY 27, 1964 (2D)

## Dọkita Chike Obi Nlọ Ṣe Ipade Ni Peking

Ni ọjọ Abameta ti le ọjọ kẹdogbọn oṣu yi ni Olori Olukọninu eto iṣiro ni ile ẹkọ giga julọ ti Unifesiti ilu Ibada tele Dọkita Chi e Obi sọ pe on ko ṣiṣẹ Olukọ mọ ni ile ẹkọ giga na ati pe on ti fi iṣẹ na silẹ patapata

Dọkita Chike Obi tun fi ye awọn Oniwe Irohin pe otitọ ni onfi iṣe Olukọ silẹ ṣugbọn ko si da on duro nipa ẹkọ eto isiro rara Dọkita Obi tun sọ pe nisisiyi pe on wa nipa eto iṣẹ ọrọ Oṣelu ati bayi on si ngbiyanju lori eto iṣiro.

Dọkita Obi sọ pe on si wa ninu ẹgbẹ eto nipa iṣiro ati pe awọn igbimọ na ni yio ṣe ipade ninu oṣu to mba yi ati pe ipade na Dọkita Obi sọ pe on ni lati fi iwe kan han lori eto iṣiro fun awọn ọmọ ẹgbẹ na

Nigbati Dọkita Obi nba awọn Oniwe Irohin nsọrọ lori ipade ti yio lọ ba wọn ṣe ni ilu Pakieg ti awọn oniwe Irohin si nbere ọpọlọpọ ọrọ lọwọ rẹ Dọkita si kọ delẹ lati dahun awọn ibere na tan

Dọkita Obi sọ pe oda on loju pe on yio gba Ijọba ipinlẹ Ila Orun Naijiria lọwọ awọn ẹgbẹ Alakukọ N C N C ninu Ọdun 1966 Dọkita Obi tun nfi ye awọn Oniwe Irohin pe awọn ẹgbẹ Alakukọ ko le wọle ninu idibo si ile Igbimọ Aṣofin ti Ijọba apapọ

## "Bi Ajọṣepọ N. P. C. Ati N. C. N. C. Ba Bajẹ, Ngo Fi Aye Mi Silẹ"

# ỌRỌ NA DE OJU RẸ, ỌLỌLA AZIKIWE FARAYA

NSUKKA:— Ibanujẹ doriko agba kodo ni ọrọ mabakungbe ti Ọlọla Nnamadi Azikiwe Olori Apapọ Ijọba Naijiria sọ fun Ọgbẹni Eje Agbo Olotu Iwe Irohin "Nigerian Citizen" Iwe Irohin ti iṣe agbọrọsọ Ijọba Ipinlẹ Ariwa, pe, on (Zik) di Olori Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria lori adehun ajọsepọ larin ẹgbẹ Olomi (N P C) ati ẹgbẹ Alakukọ (N.C.N.C.) lẹhin ibo atundi ninu ọdun (1959) idunrun

Ọlọla Azikiwe tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ pe, iwe oriṣi meji ni awọn jijọ ṣe, ọkan wa ni ọwọ on, ekeji si wa ni ọwọ Alhaji Ahmadu Bello, olori ẹgbẹ Olomi ati Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa

Ọrọ yi ni Ọlọla Azikiwe sọ ninu lẹta kan eyiti o fi ranṣẹ si ọgbẹni Eje Agbọ Olotu Iwe Irohin na.

Ọlọla Azikiwe ni, lẹnin igbati ajọṣepọ awọn ẹgbẹ mejeji wọn yi ba si tun wa ninu Ile Igbimọ Aṣofin Apapa Ijọba Naijiria, on (Zik) yio si tun wa lori aga ijoko Oye Olori Ijọba

Ṣugbọn ti ajọṣepọ eto akọsilẹ na ba bajẹ ti awọn ẹgbẹ mejeji na ko si ṣepọ mọ, on ti setan lati fi aye on silẹ gẹgẹbi olori Apapọ Ijọba.

Ọlọla Azikiwe ni, aye olori Apapọ Ijọba ti on wa loni, lori eto adehun ti awọn ẹgbẹ mejeji jijọ ṣe pọ ni, ki ise pe, ifẹ inu on ni lati wa ni aye na.

### IBINU

Oniwe irohin wa Ejongboro ti o wadi kodoro ọrọ na fi yewa wipe, Iwe irohin kan ti nwọn npe ni Out look ni Ipinlẹ Ila Orun lo kọ ọrọ kan sinu iwe irohin na lẹnulọlọ yi.

Ninu iwe irohin na eyiti Ọgbẹni C K Ajuluchukwu ti ise olotu Iwe irohin "Out-look" kọ sinu iwe irohin na

Ọgbẹni Ajuluckuwu sọ ninu iwe irohin na wipe, "Awọn enia Ipinlẹ Ariwa a maa sọ wipe awọn ni ijọba awọn dara julọ ki awọn oyinbo to de si orilẹ-ede, yi,

"Awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi ti nwọn wa ni Ipinlẹ Ariwa, a ma a sọrọ afasa ati abinuku on afojudi si Ọlọla Azikiwe ti iṣe olori Apapọ Ijọba Naijiria ni ainiye igba"

"Bẹni awọn enia na sọ wipe awọn ọmọ Hallaah, Bi o ba jẹ wipe ni totọ ni nwọn aro, ṣugbọn ko yẹ atọ mọ ara wọn ni enia le. Bi gbogbo enia yio Ọlọrun gẹgẹbi nwon ti ba tilẹ ma bu enia, a ṣe nwi, kini ṣe ti nwọn jẹ wipe, awọn adaran npegan Ọlọla Azikiwe, Lasanlasan kan ni yio ẹni Ami ororo Ọlọrun" ma bu enia. Tabi iṣẹ

"Bi ko ba jẹ wipe, wo ni awọn enia Ipinlẹ Ariwa tun ni ti o ju ki a tilẹ dakẹ, o yẹ ẹnigbogbo ki o yọwọ iṣẹ adaran lọ ?"



DOKITA NNAMDI AZIKIWE
Olori Apapọ Ijọba Naijiria



Alhaji Ahmadu Bello
Olori Ẹgbẹ Olomi

Ọgbẹni Ajuluchukwu tun sọ siwaju ninu ọrọ wipe, "ohun ti o mbi awọn enia Ipinlẹ Ariwa ninu ni ọrọ ti Ọlọla Azikwe sọ ninu Ile Ẹkọ Unifasiti Nsukka, pe, o yẹ ki Apapọ Ijọba ṣe atunse eto ofin iselu orilẹ ede Naijiria, ki awọn ayipada diẹ-diẹ si wa ninu awọn ofin na

Ọgbẹni Ajuluchukwu wa bere lọwọ awọn enia na pe, "Kini o nba awọn Lagido Omugo Ọbọ adaran lasanlasan ti Ọlọla Aziwe sọ yi?

"Allah (Ọlọrun) paa pa mọ tẹlẹtẹlẹ, o si ti ri awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi ko yan wọn ni olori Apapọ Ijọba, ki o to yan Ọlọla Azikiwe, olori Apapọ Ijọba si aye na'

"Nitorina, ọmọ ẹgbẹ Olomi ti o ba gbojugboya ti enu rẹ ba si gbọrọ ti o mbu Azikiwe, ki o mọ daju pe, Azikiwe kọ ni on mbu bi ko ṣe Ọlọrun ti oyan Azikiwe"

"Bẹni Ọlọrun na ko ni dakẹ l'ọrun, yio se ẹtọ ti yio ni jẹ wipe, ẹni egbe ni Oluwa rẹ yio jẹ niwaju Ọlọrun, nitori ọrọ Blasfemi ti Oluwa rẹ nsọ"

"Lotọ, lotọ ni mo sọ fun nyin, Ọlọrun Nla ti gbogbo enia nsin wa loke, yio si ṣe idajọ awọn ọmọ ẹgbẹ Olomi"

Ọgbẹni Aja'uchukwu tun sọ pe, "Bi enia ba nyọ ilẹda ohunbu buru a maa yọ oluwarẹ ṣe Ọlọrun ti se idajọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ olomi

Wo Oju Ewe Kẹfa

# Ijọba Ko Ti Faramọ Ida duro Owo-Oșu Ọba Olukare

IKARẸ:— Ni ọjọ Abamẹta ti ișe ọjọ kẹdọgbọn Osu yi ni irohin de ọwọ wa pe Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ko ti faramọ owo-ọșu Ọba Amusa Mọmọh, kẹta Oluka rẹ ti ilu Ikarẹ eyiti igbimọ afunishọ ti Ijọba ibilẹ ilu Ikarẹ fi sọ pe ki nwọn ki nwọn da owo oșu Ọba na duro fun Oșu mẹfa

Irohin na de etigbọ wa lati ẹnu Adele akọwe eto owo ti Ijọba ibilẹ ilu na Ọgbẹni S. S Esan pe Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ko ti faramọ owo-oșu Ọba na ti awọn igbimọ afunișhọ na sọ pe nwọn yio da duro fun oșu mẹfa.

Awọn igbimọ afunișhọ ti Ijọba Ibilẹ ilu Ikarẹ șe ipinnu yi ninu ipade kan ti nwọn șe ninu ọsẹ to koja ti nwọn fi ẹsun kan Ọba Mọmọh pe o nlọwọ ninu eto oșelu eyiti awọn igbimọ na fi sọ pe nwọn yio da owo-oșu Ọba na duro fun oșu mẹfa.

Awọn ọmọ ile igbimọ afunișhọ na tun fi ẹsun kan Ọba Mọmọh kẹta pe awọn ọmọ ẹgbẹ oșelu kan sọ Aafin rẹ di ibi ile ipade ti awọn ọmọ ẹgbẹ oșelu na ti nșe ipade

Ninu ọrọ ti Adele akọwe eto owo fun Ijọba ibilẹ ilu Ikarẹ Ọgbẹni S. S. Esan tun fi ye oniwe ironin wa to wa ni Ikarẹ pe awọn igbimọ aunișhọ ti Ijọba ibilẹ ilu Ikarẹ ti mu ẹsun eto lati da owo-oșu Ọba na duro fun oșu mẹfa șugbọn Ọgbẹni Esan tun sọ pe awọn ko ti le sọ pato boya Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun yio faramọ nkan ti awọn igbiafunișhọ na sọ nipa ẹsun ti nwọn fi kan Ọba Olukare ti ilu Ikarẹ.

# Yẹ Irawọ Rẹ Wo

AQUARIUS (Jan 20 - Feb 18) Gbogbo ișẹ ti o wa niwaju rẹ ni o șe yanju loni pẹlu irọwọ rọse, șugbọn mașe yaju si awọn ti o ba ju ọ lọ.

PISCES (Feb 19 - Mar 20) Mașe lo asiko rẹ lori ișẹ ti o mu ibinu wa fun ọ, o gbọ irohin ayọ kan loni ki ilẹ to șu.

ARIES (Mar 21 - April 19) Okeișoro ti o wa niwaju rẹ o di pẹtẹlẹ loni ti o ba le farabalẹ șe ișẹ rẹ dada, masi șe pa ișẹ kankan ti loni.

TAURUS (April 20 - May 20) Owo așejere wa fun ọ loni, ati arisiki ti o ba le sunmọ awọn ọrẹ ati ẹbi rẹ.

GEMINI (May 21 - June 21) Ailera wa fun ọ loni, șe pẹlẹpẹlẹ ki o si tọju ara rẹ, ilera ni ogun ọrọ.

CANCER (June 22 - July 22) Gbiyanju lati san gbogbo gbese ti o ba jẹ ki ọwọ rẹ o le to gbogbo nkan ti o ti nnaga lati mu ni ọjọ pipẹ.

LEO (July 23 - Aug 23) Fi pẹlẹpẹlẹ șe ișẹ rẹ loni ki o ma ba șe padanu ohun ti o șọwọn fun ọ.

VIRGO (Aug 23 - Sept 22 Șọra pupọ pẹlu iwa jagi dijagan ki o ma ba șe tẹ lọwọ ẹniti o fẹran rẹ tan. ki o si tun kapa awọn enia miran ti o wa yi ọ ka.

LIBRA (Sept 23 - Oct 23) Awọn ișẹ ti o ba șe pata ki ti o wa niwaju rẹ ni ki o tete kọ șe ni owurọ yi ki o ma ba padanu ohun pataki kan.

SCORPIO (Oct 24 Nov 22) Fi aye silẹ diẹ loni lati ba olulẹ rẹ șere, masi se lo gbogbo asiko rẹ lori ișẹ kan; ara nlẹ isimi.

SAGITTARIUS (Nov 23 - Dec 21) Awọn ișẹ ti o ba șe ni owurọ yi, nitori ailera diẹ yio wa fun ọ ki ilẹ to șu ti ișẹ kan ko si ni wu șe mọ, Aigbọnran san ju ẹbọ lọ.

CAPRICORN (Dec 22 - Jan 19) Ko si wahala kankan fun ọ loni, Orire si wa fun ọ lẹnu ișẹ rẹ, iwa pẹlu aiye nlẹ, ma si șe gbẹkẹle ẹnikan aiye le.


GBANGBA DẸKUN! KEDERE BẸWO!!




Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ e lenu on akan bi odun kan tabi jubẹ lo awọn egbogi rọl irọbi fun le se iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ se owo ofo mọ

Bere fun egbogi awọn ara Ilu Faranse ti wọn npe ni PORAL ojulowo hanunhanun, a amatase egbogi fun Iko otutu, Ikọ ọna ọfun, Iko Igbaaya, Iko iile. Ikọ ti o mọ mu enia tu kẹ ẹbẹ nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungsa tabi ti o ba nmu enia ru pẹlu.

Bi o ba ran Igo kan PORAL yi wa Iwọ na yio ri i pe to ninu ara rẹ ni kiakia Igbaaya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio si san ni patapata iwọ yio ma jeun dara dara iwọ yio si un fọnfọn pẹlu alafia de.

Bere egbogi yi ni awọn orisiri ibi gi Ikọ miran ni Șọbu awọn:—

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square, Lagos

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọjalta Paji) ... ....

Adedun Chemist
14, Wakeman Street, Yaba

ATI NI AWỌN ȘỌBU OLODUMARE DISPENSARY
IȘẸ IBADAN



Bi O BA NI
Iwe—Titẹ
FUN
Lilo nibi Ișẹ rẹ tabi orișiriși iwe itufọ tabi ijade Oku
ATI
Iwe Igbeyawo
KỌWE SI ILE—IȘẸ—ERỌ ITẸ IWE
Modupẹ Printing Press
16 Bamgboșe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos

KETEKETE NI ERỌ ITẸWE WA NHAN
OWO POOKU NI A SI NGBA

IROHIN KO TO AFOJUBA
Oun wa wa lẹẹkan șo ko si ri iyato

# Eyi ni awọn ọjọ Ọja Ilẹ Yoruba

## ỌJỌ AJE JULY 27 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikeja, Agege, Ebute-Ero Ojo Ajọ |
| ABẸOKUTA | Lafenwa, Ọbada, Ọba, Kajọ |
| IBADAN | Ajegunlẹ, Idọgọ Olodo Lalupon, Ajegunlẹ Owode Igbo-Igbo-Ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Ago-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imodi |
| IJẸSHA | Ijẹbu-Ijẹsha Iwara, Ejiro, Odo, Ibokun, |
| ẸGBADO | Lasilo, Idiẹmi |
| EKITI | Okemesi Ifaki |

## ỌJỌ IṢẸGUN JULY 28 (TUESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo, |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Iberẹkodo, Aṣu, Wasinmi Owode |
| IBADAN | Akeroro, Idọfin, Lagun, Ṣagbẹ, Ogunjau, Motelete, |
| IJẸBU | Aiyepe, Ṣagamu, Itaoṣu Ogere, Irolu, Itelu Ode-Remo Oyingbo |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla, Imesi Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilaro, Ọja-Ọdan, Sunwa Iboro |
| EKITI | Ilogbo, Ishan |

## ỌJỌ'RU JULY 29 (WEDNESDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ọbun-Eko, Ojuwoye, Ikosi, Epẹ |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbado, Ifọ, Itori, Itoku Iṣabọ Odẹda, Ibara, Kila, |
| IBADAN | Fedegbo, Oyedeji Ogunuro, Ẹgbe Babalokuta, Ijaiye-Ọrile |
| IJẸBU | Ilishan, Iṣara, Imodi |
| IJẸSHA | Ẹpẹ Iọbaimuroko, Erinm |
| ẸGBADO | Ayetoro Ado Odo |
| EKITI | Egosi Odo-Aiyedun. |

## ỌJỌ ỌJỌBỌ JULY 30 (THURSDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin, |
| ABẸOKUTA | Otta, Abalabi, Ṣodẹkẹ, Omi'ad Ilawọ |
| IBADAN | Ituko, Sojukonko, Tọwọbo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun —Ọwa, Ẹruwọn, Omu Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo, Idoko Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila Ijọun, Imasai Owode |
| EKITI | Oke-Aiyedun, Ikọle |

## ỌJỌ ẸTI JULY 31 (FRIDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Ikeja, Agege Ebute—Ikorodu |
| ABẸOKUTA | Lafẹnwa, Ọbada, Ọba, Kajlde |
| IBADAN | Ajegunlẹ, Idọgọ, Olodo, Lalupọn, Ajegunle, Owode Igbo-Ọra |
| IJẸBU | Ibẹfun, Atikori, Imushin, Agọ-Iwoye, Ijẹbu-Ijẹsha, Iṣara, Imode |
| IJẸSHA | wara Ejiro, Odo, Ibokun Ijẹbu-Ijẹsha |
| ẸGBADO | Lasilọ-Idiẹmi |
| EKITI | Ikemẹsi, Ifaki. |

## ỌJỌ ABAMẸTA AUGUST 1 (SATURDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Oyingbo, |
| ABẸOKUTA | Ijoko, Bẹrẹkoko, Aṣu, Wasinmi Owode |
| IBADAN | Akeroro, Idọfin, Lagun, Ṣagbọ, Ogunjau Mọlete, |
| IJẸBU | Aiyepe, Shagamu, Itaoṣu Ogere Irolu Itele, Ode-Rẹmọ, Oyingbo |
| IJẸSHA | Ibodi, Ibode, Kajọla Imẹsi-Ile |
| ẸGBADO | Alagba, Ilaro, Ọja-Ọdan, Sunwa Iboro |
| EKITI | Ilogbo Ishan. |

## ỌJỌ AIKU AUGUST 2 (SUNDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBERẸ | Ọbun—Eko, Ojuwoye, |
| ABẸOKUTA | Atan, Agbabo, Ifọ, Itori, Itoku Isabọ, Ọdẹda, Ibara, Kila |
| IBADAN | Pẹdẹgbọ, Oyedeji, Ẹgbẹda, Babalokuta, Ijaiyẹ—Ọrilẹ |
| IJẸBU | Ilishan, Odogbolu, Atan, Imọpe Iṣara, Imọdi, Ishan, Akẹsan, |
| IJẸSHA | Ẹpẹ, Ilọba, Imuroko, Erinmọọ Ilaṣẹ, Iperindo |
| ẸGBADO | Ayetoro, Ado—Odo |
| EKITI | Egosi, Odo-Aiyedun |

## ỌJỌ AJE AUGUST 3 (MONDAY)

| ILU | ORUKỌ AWỌN ỌJA |
|---|---|
| EKO ATI AGBEGBE RẸ | Mushin Badagry |
| ABẸOKUTA | Ọtta, Abalabi, Ṣodẹkẹ Omi Ilawọ |
| IBADAN | Itoko, Ṣojukonko Tọwọbowo Temidire |
| IJẸBU | Ikẹnnẹ, Ọkun-Ọwa Eruwn Omu Mamu |
| IJẸSHA | Oshu, Itagun, Odogbo Idokọ Iloko |
| ẸGBADO | Igbogila, Ijọun, Imasai, Owode |
| EKITI | Oke—Aiyedun, Ikọle |

# IROHIN KAKIRI AGBAIYE

Lati Ọwọ EJO'N GBORO

### KEFFI

Ajẹlẹ fun ẹkun Keffi ati Nasarawa Malam Tanko Yusufu ro gbo bi awọn enia ẹkun na lati gbinyanu lati gbin awọn igi ti yio mu eso tete ati ti yio mu owo wa ni agbegbe ẹkun na.

Malam Tanko sọ ọrọ rẹ nibi ti nwọn ti nse eyẹ awọn igi ti yio mu eso wa. Malam Tanko si tun rọ gbogbo enia to wa ni ẹkun na lati le gbin yanju bi awọn na yio se ni ipin ti wọn ninu eto igi gbigbin na.

### LONODONU

Laipẹ yi ni irohin de eti gbọ wa pe akọbi ọba binrin ilu Gẹẹsi ọmọ ọba ti ilu wa sọ pe aran numonia nyọ lẹnu bayi ati pe o ti nlọ fun itọju ni ile iwosan kan ati pe awọn ẹgbokangi Dokita 'o si nfun ni ogun lati ma lo fun itọju ara re

### EKO

Ni dede agogo meji abọ ọsan ni mọto ayọkẹlẹ kan nọmba L.G505 olu igi mọ ngoro kan ni odikeji ile isẹ ẹro asọrọ mongoesi ni Ikoyi

Irohin awọn Ọlọpa fi ye wape oni mọto na si fara pa pupọ sugbọn lẹsẹkẹsẹ ni nwọn gbe Ọkunrin na lọ si ile iwosan ni Eko lati lọ se itọju rẹ

### APAPA

Ni dede agogo marun irọle ni jamba mọto kan sẹlẹ ni oju ọna Apapa pẹlu moto ayọkẹlẹ kan eyiti awọn Ọlọpa ko ti mọ nọmba mọto rẹ pẹlu ọkunrin kan Josiah Nwagugu to si fara pa pupọ sugbọn lẹsẹkẹsẹ ni awọn Ọlọpa gbe ọkunrin na lọ si ile Iwosan L'Eko lati lọ se itọju rẹ

### IBADAN

Gbogbo adugbo ni ilu Ibadan ati agbegbe rẹ ni okun fun ọpọlọpọ omi eyi ti omu ki awọn ile itaja miran kun fun omi ninji ojo nla kan to sẹlẹ laipẹ yi

Ninu awọn adugbo ti ẹkun omi na ti sẹlẹ ni Idikan Ogunpa, Oke Padre ati adugbo Lebanon

